# IBẸRẸ IDAJỌ LORI EGIPTI

## Ẹksodu 7:14-25; 8:1-19

## ẸKỌ 53 FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ibukún ni fun ẹniti o bẹ̀ru nigbagbogbo: ṣugbọn ẹniti o ba sé aiya rẹ̀ le ni yio ṣubu sinu ibi" (Owe 28:14).**

**I Idajọ Kinni: A Sọ Omi Di Ẹ̀jẹ̀**

1. A sọ fun Mose lati kede idajọ Ọlọrun kinni, eyi ti a ran ki awọn ara Egipti ba a le mọ̀ nipa Oluwa Jehofa, Ọlọrun Israẹli, Ẹksodu 7:14-19; 9:14-16; I Samuẹli 4:7-9; Jọṣua 2:9-11; II Kọrinti 4:3, 4
2. Mose ati Aarọni gbọran si Ọlọrun a si rán àrun naa bi Farao ati awọn iranṣẹ rẹ ti n woye, Ẹksodu 7:20, 21; Orin Dafidi 78:44, 45; 105:29
3. Awọn alalupayida gbiyanju nipa idán wọn lati bu ẹnu ẹ̀tẹ́ lu iyanu yi, Farao si tun sé ọkan rẹ le, Ẹksodu 7:22, 23; Matteu 24:24; Deuteronomi 13:1-3; II Tẹssalonika 2:7-12; Ifihan 13:12-15
4. 4 Arun naa mu ìpọnju nla ba wọn ni Egipti, Ẹksodu 7:24, 25; Gẹnẹsisi 15:13, 14; Ifihan 16:3, 4

**II Idajọ Keji: Arun Ọ̀pọlọ́**

1. A kilọ fun Farao pe idajọ miran n bọ̀, Ẹksodu 8:1-4
2. A kede idajọ naa a si ran awọn ọ̀pọlọ si Egipti, Ẹksodu 8:5, 6
3. Awọn alalupayida tun fi idán wọn ṣe bẹẹ, Ẹksodu 8:8-13
4. Farao bẹbẹ fun idasilẹ a si fi fun un lori adehun ti rẹ, Ẹksodu 8:8-13
5. Nigba ti Farao ri itura o sé ọkan rẹ le, Ẹksodu 8:14, 15; Romu 1:28, 32

**III Idajọ Kẹta: Arun Ina**

1. A sọ ekuru di iná lai kilọ tẹlẹ fun Farao, Ẹksodu 8:16, 17; Orin Dafidi 105:3l; Jeremiah 6:10; Sekariah 7:12
2. Awọn alalupayida kuna nipa idan wọn lati bu ẹnu ẹ̀tẹ́ lu iyanu naa, wọn si gba Ọlọrun Israẹli ni ajulọ, Ẹksodu 8:18, 19
3. Farao tun sé ọkan rẹ le, Ẹksodu 8:19

## ALAYE

**"Tali OLUWA?"**

Ọlọrun gbọ igbe ati imi-ẹdùn awọn ọmọ Israẹli bi wọn ti n ṣiṣẹ bi ẹrú ni Egipti, O si ran Mose lati mu wọn lọ sinu ilẹ kan ti a ti ṣeleri rẹ̀ fun wọn ni ọpọ ọdun sẹhin. Mose tọ Farao lọ nigba pupọ o si beere pe ki o gba awọn ọmọ Israẹli láyè lati lọ si aginju lọ sin Ọlọrun wọn; ṣugbọn Farao kọ̀, nitori o ro o lara lati jẹ ki agbajọ eniyan ti o wulo ni Egipti to bẹẹ lọ kuro labẹ akoso rẹ. O wi pe Jehofa, Ọlọrun Israẹli, jẹ Ẹni ti oun kò mọ̀, nitori bẹẹ ki i ṣe dandan fun oun lati gbọran si aṣẹ Rẹ̀ tabi ki oun fi oju rere wo awọn eniyan Rẹ̀. Kaka bẹẹ, Farao n fẹ ki awọn ọmọ Israẹli ṣiṣẹ́ kárakára ju ti atẹhin wa lọ.

Aáwọ̀ ti n bẹ laarin awọn ọmọ Israẹli ati awọn ara Egipti duro lori kókó ọ̀rọ kan yi. Ọlọrun Jehofa kan ha n bẹ? Bi o ba si wà, kin ni agbara Rẹ̀ ti pọ to? Kin si ni ojuṣe bi o ba wa rara, ti awọn ara Egipti ni si i? Lati fi hàn pe Oun n bẹ Oun si ni agbara, ati ki O ba le mu ileri idande awọn eniyan Rẹ̀ ṣẹ, Ọlọrun rán oriṣiriṣi idajọ wa sori awọn ara Egipti, awọn ika ati abọriṣa. Awọn wọnyi ni a n pe ni Arun Mẹwa ti Egipti.

Egipti jẹ orilẹ-ede ti o ni oriṣa pupọ. Awọn eniyan naa n sin oriṣiriṣi nkan: odo Nile, ọ̀nì ati ohun alaayè miran ninu odo naa, ẹranko ti ilẹ, kokoro, ati oorun pẹlu. Ọlọrun ran idajọ Rẹ̀ sori awọn oriṣa Egipti wọnyi, lọna kinni lati fi han fun Farao ati gbogbo Egipti pe Ọlọrun Israẹli ni Ọlọrun gbogbo agbaye ati lọna keji pe kò si Ọlọrun miran.

Ọlọrun kọkọ sọ Ara Rẹ̀ di mimọ fun Mose, ẹni ti o tun iṣẹ Ọlọrun jẹ fun Aarọni; lẹhin naa ni awọn mejeeji lọ siwaju awọn agbaagba Israẹli. Nipa awọn iṣẹ-iyanu ti Ọlọrun ṣe loju awọn ọmọ Israẹli O fi han pe Oun ni O rán awọn ọkunrin wọnyi lati ṣe akoso awọn igbekun wọnyi lọ sinu ominira. Ọkan ninu awọn iṣẹ-iyanu wọnyi naa ni a ṣe loju Farao fun eredi kan naa, ṣugbọn oun se aya rẹ le si Ọlọrun o si kọ̀ lati gba A gbọ́.

**Omi di Ẹ̀jẹ̀**

Idajọ kinni, àrun ninu eyi ti a sọ omi odo di ẹ̀jẹ̀, ni a kede ki a to ran an. Loju kan naa, bi Mose ati Aarọni ti ṣe bi Oluwa ti paṣẹ fun wọn, omi odo ti awọn ara Egipti n bọ, ti wọn si ka si mimọ́ di alai ṣe e lò. Tẹlẹtẹlẹ o jẹ omi ti ko ni abuku ti o si dara fun mimu, nigba gbogbo, o mọ gaara o si n dan, ayafi ni akoko ikun-omi nikan, -- ṣugbọn nisinsinyi o di kiki ẹ̀jẹ̀.

Niwọn bi omi ti jẹ kò ṣe e ma ni fun ẹmi eniyan, ti ẹranko, ati ti eweko ni ilẹ ti o mooru yi, awọn ara Egipti ka odo Nile si ọkan ninu awọn ti o ṣe pataki julọ ninu ẹgbẹgbẹrun awọn oriṣa ti wọn n sin. Nitori bẹẹ arun kinni funra rẹ jẹ idanwo nla ti o mi awọn oriṣa wọn ati ẹ̀sin wọn kijikiji. Bi Ọlọrun Israẹli ba le sọ omi Nile di ẹ̀jẹ, yoo jẹ ohun ti o hàn kedere fun awọn ara Egipti pe Oun lagbara ju odo ti awọn ka si oriṣa pataki.

Ṣugbọn Satani, olutanjẹ nla ni, ri i pe awọn iranṣẹ oun wà nibẹ lati gbiyanju lati bu ẹ̀tẹ lu gbogbo iṣẹ-iyanu ti a rán lati fi yé awọn eniyan wonyi pe Jehofa ni Ọlọrun otitọ, ani Ọlọrun kanṣoṣo ti O wà. Awọn alalupayida Egipti si fi idán wọn ṣe iru iṣẹ-iyanu kan naa; lai si aniani nitori iṣẹ wọn ọkàn irera ati ọkan agidi Farao di lile si i. Boya o gbero rẹ wi pe niwọn bi awọn eniyan oun ti ṣe irú iṣẹ-iyanu ti a rán lati fi agbara Ọlọrun hàn, ko si nkan ajeji ninu iṣẹ-iyanu naa, nitori naa ko le si ohun ti o ṣe abami ninu Ọlọrun Israẹli tabi agbara Rẹ̀.

**Ọpọlọ Lati Inu Odo**

Arun keji jẹ eyi ti ki i ṣe pe o da awọn ara Egipti laamu nikan ṣugbọn ti o ṣe iparun laarin wọn pẹlu (Orin Dafidi 78:45). Awọn ọpọlọ ti inu odo jade wá o si fẹrẹ jẹ pe ibikibi ti eniyan le ronu rẹ ni a ti ri wọn lori ilẹ naa. O ṣoro lati fi ọkan ro bi àrun ti o ri ni lara yi ti pọ̀ to tabi iru wahala ati irẹwẹsi ti o mu wá.

Ọpọlọ jẹ ọkan ninu awọn oriṣa Egipti, a si tun le ri ninu àrun yi bi ọwọ́ Ọlọrun ti lodi si isin ibọriṣa wọn. Farao bẹ Mose pe ki o gbadura ki arun naa baa le kuro – nipa bayi o gba wi pe Ọlọrun Israẹli tobi ju eyikeyi lọ ninu awọn oriṣa Egipti. Nipa adura Mose awọn ọpọlọ naa kú olukuluku si ibi ti o gbe wà, eyi ti o fi ontẹ ti o mu ni lọkan ju bẹẹ lọ, ti o hàn gbangba, ti ko si ṣe e gbagbe jẹ iṣẹ-iyanu naa, ju wi pe ki awọn ọpọlọ naa ṣadede – bi o tilẹ jẹ pe lọna iyanu – pada si kọ̀rọ̀ ibi ti wọn maa n gbe.

Gbigba ti a gbà fun Farao lati yan akoko ti a o mu arun naa kuro tun jẹ iṣipaya miran ti a ran si i pe kò si agbara kan yatọ si agbara atọrun wá ti o le wà nidi iṣẹ-iyanu naa. Rira ti oku ọpọlọ naa rà tun jẹ ohun iran-ni-leti si i pe oriṣa ọpọlọ Egipti kò ni agbara kankan funra rẹ, ati wi pe ni gbogbo ọna ni o fi wà labẹ akoso Ọlọrun Israẹli.

**Ina Lati Inu Ekuru**

Gẹgẹ bi arun omi ti a sọ di ẹjẹ ti ṣẹlẹ lẹhin igba ti ikilọ ti jade pe arun naa n bọ bakan naa ni a ṣe ran arun ọpọlọ wá; ṣugbọn idajọ ẹkẹta – arun iná -- ni a ran jade lai si ikilọ tẹlẹ. O dabi ẹni pe gẹgẹ bi idajọ ojiji ni a ran an sori Farao ọdalẹ ati awọn eniyan rẹ. Iná ti inu erupẹ funra rẹ jade o si dá eniyan ati ẹranko lóró jakejado ilẹ Egipti. A sọ pe awọn ara Egipti, yatọ si ọpọ orilẹ-ede abọriṣa miran, jẹ onimọtoto eniyan gidigidi ti o ni iduro ti o ga rekọja nipa imọtoto ti ara ninu ẹsin ibọriṣa wọn, bi iná ba si wà lara wọn, eyi a sọ wọn di alai mọ fun ijọsin wọn.

Eyi jẹ opin igbiyanju Satani lati bu ẹtẹ lu iṣẹ-iyanu nipa ṣiṣe iru awọn arun naa. Awọn alalupayida kò le ṣe iru arun bi arun iná, wọn si fi idanú ara wọn jẹwọ pe ika Ọlọrun ni eyi jẹ. Niwọn bi o tilẹ jẹ pe awọn alalupayida wọnyi tikara wọn ni o wi pe ki i ṣe ẹlomiran bi ko ṣe Ọlọrun Israẹli ni o ran arun yi wa, eyi tun fi hàn fun awọn ara Egipti ati fun gbogbo eniyan ni igbakuugba pe Ọlọrun yi ni o ga rekọja ju lọ. Awọn oriṣa naa ti abuku kan wọnyi kò tilẹ le ṣa ipa kan rara lati fi opin si i tabi lati din arun yi ku lọnakọna, eyi ti kò jẹ ki o ṣe e ṣe fun awọn abọriṣa wọnni lati ṣe ijọsin itiju ati ailọla wọn.

**Aanu Ti N Bẹ Ninu Idajọ Isinsinyi**

Ọlọrun rán arun wọnni lati da Israẹli silẹ ṣugbọn O tun ran wọn ninu aanu Rẹ̀ si awọn ara Egipti, ki wọn baa le mọ pe oriṣa ti awọn gbẹkẹle ko lagbara rárá lati gba wọn. A fi hàn kedere pe bi o tilẹ jẹ pe awọn alalupayida wọnyi ṣe iru meji ni ọna kekere ninu arun mẹwa naa, sibẹ wọn ko le yi eyikeyi pada ninu wọn, tabi ki won tilẹ ṣe aṣeyọri ọkan ninu wọn. Ohun iyanu ti Ọlọrun fi han yi ti ṣe iṣẹ ti Ọlọrun n fẹ ki o ṣe lọna kan nipa wi pe awọn alalupayida funra wọn jẹri pe ika Ọlọrun ni o mu arun ina wa (Ẹksodu 8:19); lọna keji, nitori pe awọn iranṣẹ Farao ti o bẹru ọrọ Oluwa ti wọn si gbọran si ọrọ naa ni a dási kuro ninu ajalù arun yinyin (Ẹksodu 9:20, 21); lọna kẹta, nitori pe o kee tan fun igba kan, awọn iranṣẹ Farao bẹ ẹ lati gba ibeere Mose nitori pe wọn bẹru ohun ti o le de bi oun kò ba ṣe bẹẹ (Ẹksodu 10:7).

Nipa bẹẹ, a n mọ̀ Ọlọrun nipa idajọ Rẹ̀, nitori pe ninu gbogbo iṣe si ọwọ Rẹ̀ nipa igbesi-aye eniyan ipinnu Rẹ̀ ni lati tàn imọlẹ si ọkan wọn ki O ba le mu wọn kuro ninu igbẹkẹle ohun asan wá sinu igbẹkẹle ninu Oun nikan ṣoṣo; nipa gbigba wọn là kuro ninu iṣina ati ẹ̀ṣẹ, ki wọn ba a le di ọlọgbọn, ẹni mimọ́ ati ẹni ti o ni ayọ. A ti sọ wi pe nigba ti idajọ Ọlorun ba wà lode awọn olugbe ori ilẹ a kọ́ ododo. Bawo ni o ti yẹ ki a dupẹ tó pe Ọlọrun n ba awọn eniyan ati orilẹ-ède lò lọna bayi, O n dú u lati mu gbogbo wọn wa sọdọ Oun tikara Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1. Ṣe apejuwe arun meji akọkọ.
2. Eeṣe ti o fi jẹ pe awọn arun wọnyi gan an ni Ọlọrun fi kọlu Egipti, kin ni a si doju wọn kọ?
3. Kin ni arun kẹta?
4. Kin ni a rò pe o ṣe ti a fi rán arun yi gan an, kin ni o si dabi ẹni pe o di awọn ara Egipti lọwọ lati ṣe?
5. Iṣẹ Satani wo ni o fara hàn nigba ti a mu awọn iṣẹ-iyanu mẹta wọnyi ṣẹ?
6. Mose ha kọju'ja si, tabi ki o gbiyanju lati tú aṣiri awọn ifarahan iṣẹ Satani wọnyi?
7. Awọn alalupayida ha ṣe aṣeyọri ninu igbiyanju won lati lo agbara wọn?

8. Iha wo ni Farao kọ si ọkọọkan ninu awọn arun mẹta wọnyi?
9. Lọna bawo ni a ti le sọ pe ninu aanu ni a rán awọn idajọ wọnyi?

A ha kọ́ ni lati inu Iwe Mimọ́ pe awọn idajọ wọnyi tu irun kankan lara awọn ara Egipti?